Àpèjúwe ẹniti nrántí Olúwa rẹ ati ẹnití kò rántí Olúwa rẹ da gege bi alàáyè ati òkú ni

Láti ọdọ baba Musa - kí Ọlọhun yọnu si i - o sọ pé: Anọbi (ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ máa ba a) sọ pe: "Àpèjúwe ẹniti nrántí Olúwa rẹ ati ẹnití kò rántí Olúwa rẹ da gege bi alàáyè ati òkú ni ", gbólóhùn ti Muslim ni" Àpèjúwe ile ti wọn ti nranti Ọlọhun, ati ile ti wọn kò rántí Ọlọhun níbẹ o da gẹgẹ bí alaayè ati òkú ".

[O ni alaafia] [Ohun ti wọ́n fi ẹnu kò lé lórí ni]

Anọbi ki ikẹ Ọlọhun ati ọlá Rẹ má bà nsalaye iyatọ to wa láàrin ẹni ti nranti Ọlọhun ti o ga jù ati ẹni tí kò rántí Rẹ, ati pé gẹgẹ bí iyatọ tó wà láàrin àlàyé ati òkú ni bi iwulo rẹ ati didara irisi rẹ, àpèjúwe ẹni ti nranti Olùwà rẹ ọ da gẹgẹ bí aláayè ti ìta rẹ gbé ẹṣọ jáde pẹlu imọlẹ iseni , ati inú rẹ pẹlu imọlẹ ìmọ, ìwúlò n'bẹ lára rẹ, àpèjúwe ẹni tí kò rántí Ọlọhun o da gẹgẹ bí òkú ti ìta rẹ ti da ṣẹlẹ ti inú rẹ sí ti bajẹ, bẹẹ ni kòsí ìwúlò kan kan lára rẹ mọn. Bẹẹ náà ni ilé wan royin rẹ pẹlu isemi (aláayè) ti awan olùgbé rẹ bá nranti Ọlọhun, ti wan ba rántí Ọlọhun a jẹ pé òkú ni ile náà kúrò níbi ìrántí Ọlọhun, ti wan ba lo aláayè ati òkú lati fí royin ile ẹni ti o gbe bẹ ni wan fi ọrọ bawo.

http://sunnah.global/hadeeth/yo/show/4177